# OLO ELEJE TUTU KAN LO GB'EWA L'OGBA EWON

Drink Coca-Cola
STANDARD SIZE 4D NEW KING SIZE 6D
See that you pay the correct price.

ELETI OFE
A-NJU-WON KO SE WI L'EJO

6th & 7th BOOKS OF MOSES
LEDE YORUBA 15/
A LE RI IWE YI RA NI OSHODI COMMERCIAL SERVICE 56, KING GEORGE AVENUE YABA. ATI NI IDIKAN ROAD IBADAN

VOL. X No. 562. ELETI - OFE LAGOS, SATURDAY, MARCH 8, 1958. KOBO MEJI (2d)

## Olo Eleje Tutu Kan Lo Gb'ewa L'ogba Ewon

EKO. Ọdọmọkuerin kan ọmọ ọdun mọkanlelogun gba iwe owo ti onibara ọga re fi ranṣe, o ja iwe owo na, o si yọ owo ti o mbe ninu iwe na, ni adajọ ba sọ wipe ki o lọ gb'ewa oṣu mesan ni ọmọ na ba tu ṣuru si ekun, o wipe:-

Ejọwọ sa e wo iye ọjọ ori mi
Aṣiṣe lo je mo fe lọ silu Oyinbo.
E maṣe ba igbesi aiye mi je.

Awọn agbalagba lo npowe wipe ṣe iwọ mọ, o tiṣe ṣe. Gbogbo enia ti o ba huwa aidara kan ti o ba sọ wipe aṣe ni on ko mọmọ ki on to ṣe akan na, irọ ni oluwarẹ pa.

Adajọ dahun o wi fun ọmọ na pe on ko le jeki o lo laifi ami si ọ lara nitori irufe iwa bayi poju larin awọn ṣaṣawere ọmọde iwoyi ati papa larin awọn oṣiṣẹ Post Office nitori ti awọn afe fi ikanju di olowo.

Abọ re e Olo ni mi elejẹ tutu ogba ewọn l'o ngbehin si.,

awọn abo Pẹpẹiyẹ berẹ si ye ẹyin, obu ni ẹyin ti awọn mẹfẹfa nye. Eyi lofi han fun gbogbo enia ri pe Pawu ni akọ Pẹpẹiye, kole ṣa pata.

Kiba yi wa? bi ede awọn enia wa ni Isalẹ Eko enia ha le gba were m'esin? bi enia ko ba pe l'ara ṣe o yẹ ki o pe ninu ọpọlọ ori rẹ, Pẹpẹiye ti kole ṣa'na ye ki o jẹki ara rẹ sinmi.

Abọ ọrọ to fun ọmọluwabi.

## Ise Enia Nwu Eranko

EKO. Ohun enmọ kan ti a ri ni agbole ala kan ni Idita niti akọ Pẹpẹiyẹ kan to wa larin awọn abo Pẹpẹiẹyẹ mẹfa ti ẹaikẹni ko si mọ wipe Pawu ni akọ Pẹpẹiye na.

Lowurọ, l'oṣan ati ni irọlẹ ni akọ Pẹpẹiyẹ na ylo ma le awọn abo kakiri agbole, ṣugbọn nigbati

## Ejo Awon Apania Poju Lodunni

EKO. Lati ibẹrẹ oṣu March ni eṣi si ibẹrẹ oṣu March ni ọdun yi, 258 awọn enia lo fi ọwọ rọri ku, 179 awọn enia lo ku iku jamba, 38 ni a ko mọ ohun ti o fa sababi iku wọn.

Ninu awọn ti ko fi ọwọ rori ku, 160 ni jamba padanu, enia diẹ fi ara ṣeṣe, diẹ si pa ara rẹ. Omiran ba omi lọ, lẹntiriki pa omiran, ẹru to wuwo pa omiran Ọkọ reluwe pa omiran, Ọkọ ri awọn miran, majele si pa omiran

Oyun ṣiṣẹ pa ẹlomiran ọbẹ tabi ohun ẹlẹnu ṣoṣoro pa omiran ina jo ẹlomiran pa, beni awọn miran pokuaso funra wọn. Awọn ẹlomiran lọ sun soju irin, awọn miran fi ọbẹ ge ara wọn ni ọna'fun.

Ejọ apania ti awọn ọlọpa ṣe ni ọdun to koja jẹ 387, ejọ awọn ti o ṣeṣi pa enia jẹ 264. Ejọ awọn ti o gbero lati pa enia ti ko ri aye to jẹ 202, ṣugbọn awọn ti o mọmọ pa ara wọn jẹ 1,936.

Awọn ti o gnabẹ jẹ 9,780 Ija 6,454, Ọwọ ọlọpa ba ọkunrin agbẹ kan ti o da oko ewe taba kan ti nwọn npe ni Igbo ni oko Abẹokuta.

## Oloye Akintola Fi Ero Isoro Titun Ba Sardarna Soro

Awọn igbimọ P&T ṣe ẹrọ iṣoro kan ninisiyi ti o jẹ wipe ibikibi tabi ilu kilu ti o ba ti ṣe pataki ni enia le ba sore lori ẹrọ isọrọ kan ti nwọn ṣese ṣe pari ti nwọn npe ni (Telecommunication) Lori ẹrọ yi, ẹniti o mbẹ nilu Eko le ba Ṣokoto, Katsina Nguru Boronu tabi Kameru ti nwọn mbẹ ni ọna jijin rere ti nwọn ju ẹgberun busọ lọ sọrọ. Nigbati ẹrọ yi ṣe tan fun lilo, Oloye Akintola ti o nṣe Minister fun Iṣe na fẹ danwo.

S L A - Gbọran gbọran gbọran
Olotu - (Eyi ni operator to wa nidi ẹ)

(Wo yoku loju ewe kejo)

## Oloye Akintola P'agbo Sebe Oyinmomo

Ki awon, egbe osise P & T wa gba ki nwon to wo, oyinmomo, ni orin ti o ye ki a ko si inafo apeje pataki kan ti Oloye S, L, Akintola ti ise Alabojuto ile ise Ifiwe-ranse ati Oko ofurufu (Minister of Communications & Aviation) pe ni ijo o Ruruba Wednesday) ose yi fun awon osise Post & Telegraphs ti o ti gba isinmi il'ehinti gbowo (Pensioners) ni gbangba teju iwaju ode ile igbimo nla (Frontage of the House of of Representatives) to fi se akojo ilenukenu ebi osise ile ise P&T na, nitoripe lati igbati Olukuluku awon osise enia na ti gba isinmi ifehinti kuro lenu ise ni ko ti si anfani ipapo be larin won mo.



Ibi apeje na dun o si ni arinrin nitoripe eniti kole rin ni ki nwon gbe on ese awon agbowo ifehinti pe siba-siba, sibe Alagba Ogbeni Stavely ti P&T igba rere atijo ba won debe pelu.

Oloye Akintola ba won soro to dun mo won ninu to fi je wipe gbogbo won l'o nda muso re.

Iyesi ojo na po fun S L A tiwa.

# Orisa Kan Ti O Tun Pada Wa Saiye



Ohun ti a nwo ninu aworan yi ni ere orisa kan ti nwon ol bo mole ni ile Ife, sugbon nigbati awon P. W. D. nwa erupe lati fi di awon koto ti o wa ioju ona moto ni nwon ri ere ti a nwo yi hu nile. Opolepo enia so pe Obalufon ni, omiran so pe Erinle ni, beni omiran so pe on ni orisa Ogiyan.

# Adehun Ni Adehun Nje

(Lati ọwọ Dupe Odutọla)

Inu mi yio dun pupọ ti ẹ ba le gba mi laye ninu iwe irohin yin oloyinmọmọ lati sọ itan kekere yi fun awọn ọkawe wa gbọ.

Ni aiye atijọ ni ilu kan, ọkunrin kan wa ti apeja oruko rẹ nja Ṣẹnsẹ – lẹsẹ–Abaja. Orukọ yi jẹmọ ila oju rẹ tori abaja ni o kọ. Lat ọjọ ti wọn ti bi ni ewu nlaala (koko) ti wa ni ori rẹ. Awọn koko na si jẹ meje. Nipa bayi awọn enia ya sọtọ, nwọn ki isi ba rin bẹni nwọn ko gba s'ẹgbẹ kọkan.

Nigbati bi enia ba ni aisan kan lara, yio ṣoro fun lati ri oko tabi iyawo fẹ. Nitori eyi Ṣẹnsẹ-lẹsẹ-Abaja ko ni aya titi o fi di eni ọdun marundilọgọji. Lẹhin eyi, o pinnu lati lọ gbe oko. O kọ ile s'oko o si kan aaṣ sibẹ pẹlu,

O da oko repete, ohun ọgbin rẹ si emu eso wa iọpọlọpọ. Awọn ara Igboro a si ma lọ ra onje lọwọ rẹ. Ni asiko ti ojọ ibi rẹ ba sunmọ, awọn koko wọnyi a bẹrẹ si da lamu, tita ko ni to riro. Gbogbo oju rẹ yio di pipọn bi ti Alagemọ. Ṣugbọn lẹhin oṣu diẹ ara yio tu yio si ni alafia. Ṣugbọn awọn koko yi ki fi ori rẹ sile nigbana,

Ni ọjọ kan, bi o ti nroko lowurọ, ti o si nhu iṣu bẹni o kan iho ti eku afe ngbe, o si da iho na si. Nigbati o ro oko tan o pada lọ si ibiti iho eku afe yi wa, o bẹrẹ si gbẹ. Bi o ti kan agbaja iho yi bẹni eku afe meje tu si ode wọn si sa gba ọna ọtọtọ lọ Ṣẹnsẹ-lẹsẹ-Abaja ko mọ ohun ti yio ṣe o si ibu ṣẹkun o ni "Aiye mi re o tani yio ran mi lọwọ lati mu awọn eku afe wọnyi.

Lẹsẹkanna ni awọn koko ori re sọkalẹ wa nwọn si di enia, Nwọn sọ fun Abaja wipe ki o ba awọn ṣe adehun pe on ko ni salọ bi awọn ba wa awọn eku wọnyi, ki awọn si mu nwọn wa fun. Abaja pẹlu awọn koko si fi ohun ṣọkan.

Awọn alejo meje yi si gba ọna ọtọtọ lati lọ wa eku ti o salọ. Nigbati Abaja ri wipe ori on fuye, o tu puru s'ere, o si salọ si ilu miran nibiti wọn ko mọ ọ ri. Nilu titun ti Abaja salọ, o bẹresi ṣowo nibẹ o nṣa o si nra o di eniti o lowo lọwọ o kọle o si ni obinrin o bimọ ọkunrin ati obinrin.

Nigbati awọn koko wọnyi de pelu eku afe to salọ si ibiti wọn ti ṣe adehun pelu Abaja wọn ko ba nibẹ mọ o ti salọ. Nibo

(Wo yoku loju ewe keje)

# Fadayiro Di Agba Oye



Ko si bo ti ri ni, bi enia ba gun ẹṣin ninu awa Eleti Ọfẹ gerere ni ẹṣin rẹ yio sare, nigbati a gbọ irohin wipe Oloye E. A. A. Fadayiro ni ijoba Iwo Orun tun gbe ga si ipo Chief whip (eyiti a le tun mọ si Yoruba bayi pe "Suremọ") fun igbimọ Assembly.

Eyi wu wa o, Fadayiro tiwa o daju pe ewe nla ko ni ru wẹwẹ, ọwọ nyin a ran o.



# Ijagboro Ila — Orun Na Ijoba Ni Owo Goboyi

ẸNUGU- Ọrọ ẹkọ, ko ṣe ẹkọ, ti o da ijagboro silẹ ni agbegbe Ila-Orun, ṣe ndi ohun ti o kaseta. Ninu ija yi; ọkunrin mẹtaleladoje obinrin Okowolelodunrun ati ọmọde mẹdogun ni wọn ramu nipa rẹ ti ọlọpa fẹ ba rojọ.

Ninu awọn agbegbe mọkandilogbọn ti o mbẹ ilẹ Ibo, awọn agbegbe mẹtala lo lọwọ ninu ijagboro yi.

Ẹgbẹ ogun awọn ọlọpa meji ni Ijoba ran jade lati ilu Ibadan, ati ẹgbẹ ogun mẹjọ lati Eko, gbogbo wọn, ọkọ ofurufu ni wọn wọ.

Apapọ gbogbo wọn jẹ, oga ọlọpa mẹrindilogbọn ọdunrun-le-lẹgbẹrun ni awọn ọlọpa ti o lọ.

Iye owo awọn dukia ti ijagboro yi bajẹ, nlọ bi £3,300. Iye ti Ijoba yio san fun owo ọkọ ofurufu ti nwọn wọ jẹ £16,600. Iye owo ona oko, ti Ijoba yio san fun ẹnikọkan ninu awọn Ọlọpa nlọ bi adọjọ poun lojumọ kan. Iye owo mọto ti Ijoba ti nlo nidi ọrọ yi to ẹdẹgbẹta Poun lojumọ kan.

Alhaji Tafawa Balewa sọ pe, eyiyi ṣe npọ ju, Ijoba Ila-Orun nilati wa wọrọkọ fi ṣe ada, ki nwọn wa ona lati mu ija na wa si opin. Nitori ẹẹlẹ, awọn ọlọpa ko ngbe ibọn agbara kaka ni a file ri wọn ki nwọn ṣe ayi.

## Akiyesi Pataki

A fi eyi kede fun gbogbo ẹnyin Aṣoju Iwe Irohin wa nilẹ Yoruba. l'oke Ọya, nilẹ Ibo, l'oke Okun ati nilu Oyinbo wipe ẹnikẹni ti ko ba fi owo wa ranṣẹ ki oṣu to pari ao kọ oruko rẹ fun Lọya Eleti-Ọfẹ, ao ba ṣe ejọ ao si gba owo iriṣẹ lọwọ rẹ.

OLOTU.


## Story of a Successful Trader

# Mr. Peter Ezeli

## and The United Africa Company work together for prosperity





Since leaving school, Mr. Peter Ezeli has built up a flourishing cycle business, with stores in Warri and Onitsha. At first he managed the bicycle section of his father's store; then he began trading on his own account, selling spare parts and, later, all makes of cycles. But the real turning point in his life came when he agreed to take part of a U.A.C. trader's allocation of Raleigh bicycles.

In 1953 Mr. Ezeli began to deal directly with The United Africa Company, and a year later he became a credit customer. Other assistance and good advice from the Managers enabled him to prosper, and today he has a large monthly turnover. He employs a salesman and three cycle-assemblers in his new stores at Warri who work with equipment supplied by the Company. His wealth proves the wisdom of his motto, "Work hard, specialise, and thoroughly understand your trade."



*Hundreds of African traders rely on The United Africa Company to bring them goods from all over the world—and many of them started successful businesses with stock supplied on credit by the Company, helped by advice from its Managers. To The United Africa Company every trader is an important source of information on the needs of African buyers, so that both the trader and the Company profit by their friendship in business together.*

*THE UNITED AFRICA COMPANY OF NIGERIA LIMITED*

ELETI OFE
A-NJU-WỌN KO SE WI L'EJO
EDITORIAL OFFICE & WORKS CABLES & TELEGRAM
28, Kosoko Street, Lagos "ELETI - OFE LAGOS"
P. O. Box 467 Phone 23370
VOL. X. NO. 562, LAGOS, SATURDAY MARCH. 8. 1958

# Ibanuje Ko Nmu Enia Fun Ogun Odun

Maṣe banuje pupo, nigbati ọrẹ tabi ẹniti o feran julọ ba ja ọ sile gba ọna ọrun alakeji lọ. Eyiti ko ni dẹhin bọ mọ rara. Nitoripe ẹniti o kan nikanṣoṣo lo mọ, ṣugbọn awọn nyọ nitoripe nwọn ko mọ ẹhin ọla. Ẹru wiwuwo ati inawo ile di tire nikan, ṣugbọn awọn ọta rẹ nyọ, nwọn rope bẹni yio ma ri titi.

Ko si ohun ti ko ni opin, a ko ni mu ise ati ibanujẹ fun ogun ọdun. bẹni enia ko si le wa bakanna titi lai. Opin wa fun igba ẹrun bakanna ni opin wa fun igba ojo, ṣugbọn akoko ati igba ko duro de ẹnikan. Baoku iṣe ko tan igi ti o wọ ewe danu ti o si dabi eyiti o ti gbẹ ni asiko ẹrun bi ojo ba de yio tun pada ruwe.

Ọjọ kan ojo, o bori ọda, ọjọ kan ni iwọ yio ji ti iwọ yio ji sinu ayọ, nitori anu Ọlọrun gboro, ayọ yio de nikẹhin ọjọ. Bi ẹkun pẹ di alẹ kan, ṣugbọn ayọ mbọ ni owurọ. Lọjọ kan ni ibanujẹ yio fo lọ bi kurukuru awọ sanma.

Irọju ati iforiti l'ẹbọ.


# Imoran Fun Enyin Abiyamo

Enyin abiyamọ ẹ wa ra ỌMỌRELA o dara pupọ fun awọn ọmọde.

Ama jẹ ki ọmọde ri orun sun daradara o dara fun otutu, ikọ ati orisirisi arun miran ti o ma mba ọmọde ja ni asiko ehin. Ọpọlọpọ abiyamọ lo ti lo egbogi yi fun ọmọ wọn ti wọn si sọ wipe o dara pupọ fun awọn ọmọde

ỌMỌRẸLA BABY MIXTURE
(Sile Meji Abọ 2/6d Fun Igo Kan)

O wa Lọdọ
COMMERCIAL MEDICINE STORES
(Qualified Chemists)
10, VICTORIA STREET, LAGOS.


# Egbe Titun De



Ẹniti a nwo ninu aworan yi ni Alhadji Adegoke Adelabu, on ni a gbọ wipe o se idasile ẹgbẹ kan ti nwọn pe ni Yoruba Parapọ.

Ẹniti o nṣe Alaga ẹgbẹ na ni Ogbẹni N. B Soule Alhaji Adelabu paapa ni akọwe ẹgbẹ titun na.

Die ninu awọn enia ti a gbọ pe awon mbe ninu egbe na ni Oloye H O Davies, Ogbeni Joachim Oloye Kola Balogun, Ogbẹni Olowofoyeku ati Agbaje.

# Rotimi Williams Nfigbadun S'ayo



LONDON. A gbọ irohin wipe nigbati Oloye Rotimi Williams ati Oloye Ṣowole pari iṣẹ ojọ wọn tan, nwọn gbe ọpọn ayo sodo nwọn si mba ara wọn ta ayo na.

Awọn Oyinbo ti ko ri iru ohun idaraya yi ri, pe bo wọn lori nwọn si aworan bi awọn ọta meji ti se mba ara wọn taye na.

Ẹniti a nwo ninu aworan yi ni Oloye F. R. A. Williams ti o ni Ọta-Muluku-Taji ti o mba Oloye Ṣowole ti o nṣe Commissioner fun agbegbe Iwọ-Orun, ilẹ Nigeria ni ilu Oyinbo, tayo na. Eo ri i, awọn ọta meji lo to ara wọn ba ta ayo.

# Itan Awon Ogboju Ode Loke Amilala-Amilolo

APA VI

Lehin ti awọn Ogboju Ọdẹ na ji loju orun tan Alukete- fun- ogun-jo, fa ọsanyin rẹ jade ninu apo o bere lọwọ re wipe nisisiyi ti ile ṣu yi kini ewu ti o tun mbe ni iwaju fun wọn? Ọsanyin na dahun pe ogun gbigbona wa lọla nigbati ilẹ ba mọ.

Nitorina awọn ọdẹ ti gi ado olukuluku ti je egbogi aporo ap'ogun Areta Okigbẹ Aluki Madarikan Aforan Aluwo Atepa ati orisirisi Imarale Jagilegbo-se-ogun sọ wipe; Ẹnyin ọmọ iya mi nigbati iwa ṣe a ko aja ki enikan lu ẹnikeji lalode ọrun ṣugbọn nigbati aye ha fun Ẹlẹgbara ti ko ribi gba o san ara lu ọkan ninu awọn ọmọ ẹhin Oriṣa nla. Nitorina bi o ba ti gba ni ao fi jagun yi Bi o ba le di ogun ko di egun bi o ba alle dija ko dija ojo ibapa ewe koko bi o le ya ko ya. Nitori ti awa ọmọ enia ni Olodumare ṣe da aiye, o si fi awa enia jọba lori gbogbo ohun ti o mbe ninu aiye na. O si fi awa enia jọba lori gbogbo ohun ti o mbe ninu aiye na o ye ki a fi han awọn ọmọ ẹranko nwọnyi wipe Idi ni a nso Ifa mọ" Bi enia ko ba si pa iji han iji ẹru ko ni ba iji.

Gbogbo nyin ki ẹ mura bi ọkunrin alagbara lati ja ija ti ọla yi pẹlu gbogbo ohunkohun ti enia ba le fi ṣe agbara bi ilu Alọ, yi ba le fọ ejẹki a fọ o yanyan.

Nigbati ilẹ ọjọ keji mọ Afilaka ọuẹ Owọ ni ẹiyẹle kan ti o ti rọ ni oogun, o tu ẹiyẹ na sile wipe, ki o lọ kakiri ki o wa fun on ni iro ohun ti o ba ri. Ẹiyẹ

(Wo yoku loju ewe keje)

# Irohin Ipade Sinodu Ibadan

Alufa Eni - owo S. A. Banjo so ninu Ipade Sinodu ti nwọn se laipẹ yi wipe, rogbodiyan ti n agbo kakiri wipe a o pa ilẹ Ilorin rọ mọ ilẹ Yoruba nṣe idilowọ gidi-gidi fun ilọsiwaju isin Kiriyo ni agbegbe ilu Ilorin. Nitori idi eyi, Ijọba ibilẹ Ilorin ṣe ofin pe ẹnikẹni ti o ba fẹ ṣe isin ode gbangba nilati wa gba iwe ki o to ṣe bẹ. Awọn ọmọ ẹgun Igbala ti n ran lọ si agbegbe ilẹ na ninu oṣu August ni ẹsi ko ri aye ṣe isin ode gbangba fun awọn enia, nigbati awọn ko ri iwe gba.

Ọgbẹni S. A. Akinyemi ti o nṣe olofiatoto owo Igbimọ Sinodu ti o si nṣe Olotu (Principal) Ilesha Grammar School sọ wipe, bi o tilẹ je wipe Ifnachin wa ni Oshogbo ati ni Ilesha. Igbimọ yi ni owo ti o pọ to egbẹfa le ni okowo pọun silẹ mefa ati kobọ meji. Owo ti a si ndajọ fun Ṣọṣi nla alagogo to egba a din mejilelogbọn Pọun silẹ medogun ati kobọ meji.

Awọn Igbimọ Sinodu fi ohun ṣọkan pe ki nwọn lọ ri Ijọba nipa ilẹ Ṣọṣi won lẹhin ti nwọn ba ti foruko silẹ tan ki Ijọba ba won ṣetọju ilẹ Ṣọṣi. Nwọn si tun ngbero lọwọ nisisiyi lati ma fa awọn ọdọmọkunrin sinu iṣẹ Oluwa nitoripe awọn ọdọmọkunrin wa fẹ kọ iṣe isin silẹ niwa lọwọ. Iṣe Ijọba ati Iṣowo ni awọn fẹ ju.

Igbimọ ro si ohun aitọ, lati ma fi awọn ti a fi joye katikisti silẹ laifun won ni owo pataki kan lehin ti awọn ba ti dagba ju fun iṣe na lati isisiyi lo ki a fun won ni owo ti o jọju lati ṣe iranlọwọ fun won.


Eiye kan lo nke bayi pe:- B'o s'owo, joko, b'o s'owo joko Akisa aso gente-gente, Akisa aso gente-gente



## Eyi Ni Itunmo A. B. D. Olowe

Lati Owo Shakiru A Olaiya

OLOTU,

Inu mi yio dun bi Olotu ba le gba mi laye lati ma sọ itan arọgo fun awọn ẹlẹgbẹ mi ti nlọ si ile-iwe ati fun awọn okawe wa ni ọsọsẹ. Ọpọlọpọ ninu awọn elegbe mi ti wọn ka A.B.D. ti nwọn o le fi sọrọ. Emi Akọmọlede de ti orukọ mi nje Agbedegbeyọ ti inu mi kun fun ọrọ sisọ bi Odidẹrẹ ọba awọn ẹiyẹ.

Mo bẹrẹ lati ma sọ ọrọ ọgbọn ati eyi ti omu oye dani fun awọn elegbe mi lati wa fi kọ iwa hu si ara ile wọn tabi ara adugbo wọn pẹlu.

A. Abata ta kete bi ẹni pe ko ba odo tan.

B. Bẹnikan nṣe ko-ndu-kondu ko-ndu, etẹ ni yio firi.

D Darandaran, ẹiyẹ ti imu ọsan.

E Enia laṣan pọ o ju igbe eni're wọn ju oju lọ

Ẹ Ẹni mi kukute ara re ni emi

F. Fi ija f'Ọlọrun ja fọwọ lẹran.

G. Gunnugu jẹ ebọ yo Awodi jẹun epe sanra.

GB. Gbangba l'ogedegbe nṣ'awo.

H. Hiho ọsa kote t'okun

J Jijọ l'o njo dida l'onda oṣupa ko le ri bi ọsan.

K Ki arin ki apọ yiye lo nye ni.

L Labalaba ti o ba digbo l'egun aṣọ re afaya

M Ma jokun ma jekolo aiye ni ti iba ni lọ.

N Na ọmọ fun mi ko de inu ọlọmọ.

O. Oyinbo baba inaja a je baba tẹnitẹni.

Ọ. Ọpẹrẹkẹte ndagba inu adamọ nbaje modi baba tan inu bi wọn.

P Pipe li ape gbọn aki re gọ

R Riro ni ti enia ṣiṣe ni?

S Suru ni ogun aiye

Ṣ Ṣikaṣika gbagbe ajobi, adanlloro gbagbe ọla

T Tafutafa ko lagbara bi yinbọnyinbọn

U Ukuuku Gambari araba de-de ni

W Wa mi ki ng wa ọ l'ọrọ fi ndagba

Yanmuyaamu nṣe fuja lai l'apa.

## Alufa Ojise Olorun Ji Omobinrin Kan Gbe

Irohin ti a gbọ, to si yani lẹnu ni ti odidi Alufa oṣiṣẹ Ọlọrun kan ti nwọn fi sinu ẹsun wipe, o lọ ji ọdọmọbin kan gbe.

Alufa yi jẹ ẹniti o ti nṣe ikilọ fun awọn ijọ rẹ wipe, ki nwọn maṣe fi ọmọ wọn jafara, nitoripe lojojumọ ni a ngbọ iro lati ilẹ Yoruba wipe, nwọn ji ọmọ kan gbe lọ. Awọn ijọ si fi ara mọ iru ikilọ na.

A ṣe Alufa yi ti nfẹ ọmọbinrin kan soju ọna ti awọn enia ọmọde'binrin na ko fẹ ki ọmọ wọn fẹ Alufa, ṣugbọn ọmọde na na fe ki on fẹ Alufa o si gba ki Alufa gbe on lọ pamọ.

Nigbati Alufa na ngbe ọmọbinrin na salọ, awọn ti o ri i lo lọ rohin fun awọn obi ọmọ na ni nwọn ba fi ọlọpa mu Alufa ni inu Parsonage. Nigbati awọn ijọ rẹ gbọ pe ọlọpa mu Alufa ati wipe o mbẹ ni itimọle itimọle. Nwọn bere wipe, kini ẹṣẹ ti Alufa na ṣẹ,? nwọn dahun pe o ji ọmọ gbe.

Ha! ni gbogbo enia nṣe Ṣugbọn nisisiyi Alufa ti yege nwọn si da silẹ. Orukọ rere san ju wura ati fadaka lọ.


## Kere o!

Ati ni oriṣiriṣi ogun German fo ṣẹṣẹ de, fun oiruru aisan tọkunrin obinrin. Tete wa ra tirẹ ẹ'o to tan.

**J. A. AJAO BROTHERS**

MEDICINE STORES

7, Egerton Road, Lagos.


## Ibukun Ni Iranti Olododo



**O ye ki a ranti eni wa Oloye Bode Thomas Balogun ode Oyo ti o lo je ipe Olorun ni odun 1954 ni asiko ti ise owo re fe yori si rere ni olojo da si.**

**Nje niti iwo Bode Thomas mase je okun, mase je ekolo ohun ti nwon je ni aiede orun ni ki o ma ba won je.**

**sunre sunre sunre.**

## AKIYESI

### Lagos Executive Development Board

PLANNING CONTROL

Ẹnikẹni ti o ba fẹ ra ile lati fi kọle si, tabi ẹnikan ti o nile ti o si fẹ kọle sori rẹ, tabi ẹnikan ti o nile ti o si nfẹ tun ile na kọ, ni Eko nihin, a gba awọn ẹnibẹ niyanju wipe ki nwọn to se ohunkohun rara, ki nwọn wa bere wo ni ile iṣẹ Town Planning Deparment ti igbimọ Lagos Executive Development Board bawo ni agbegbe ibẹ ti ri pelu eto ile ti awọn nṣe, ki o si le mọ iru ile ti o yẹ ki o kọ sibẹ.

Ẹniti o ba fe ki o kowe bere tabi ki on papa wa si Town Planning Department ti Igbimọ Lagos Executive Development Board ni opopo Reculamation Road ni Eko lati agogo mẹjọ si agogo mẹwa owurọ lati ọjọ Monday titi di ọjọ Friday, ati lati agogo mẹjọ si mẹsan owurọ ni ọjọ Saturday.

**J. W. Henderson**

Olori Igbimo L.E.D.B.

## Itan Awon Ogboju Ode Loke Amilala-Amilolo

(O bere loju ewe kerin.)

na lo o si pada de o n on ri Kiniun ati Erin ti nwon ndira ogun on si tun ri Erin kan ti o dubulẹ aisan.

Dalemọ-fun ogun lọtọ wifun gbogbo awọn ọdẹ'wipe ki nwon ti ọwọ diju wọn nigẹju kan nigbati nwon laju, nwon ri ogun awọn ẹranko ẹru ko ba awọn ọdẹ na nṣe ni Kiniun mbu ramuramu, lẹsẹ kanna o bere si fi ito yi awọn ọdẹ na ka Ogbori-Odo-Jabi oji so fun awọn ọdẹ pe ninu ogun yi ti Ikoyi ni awọn ma fi ja. Niwon ba fa ada yọ ti nwon si nkorin bayi pe:-

He-e-e-Ikoyi o (4)

Ikoyi dorun, o mu yan yan yan o mu o dorun.

Ni gbogbo awọn ọdẹ na ba ṣi ada mọri nwọn bẹ sarin awọn Eranko awọn ẹranko paapa be lu won nwọn gba aṣọ ara Erin ti o nṣaisan gẹgẹbi nwọn ti sọ fun nwon Gbogbo ile ọba ni nwọn fọ yanga-yanga. Nwon ko Imi Ogumare Segi Iyun ati orisirisi ohun alumoni. Iyoku di ọsẹ ti o mbo.

## Adehun Ni Adehun Nje

O bere loju ewe keji

lo salọ nwọn ko mọ.

Nigbana ni nwọn lọ wa eso ikanyere ati keregbe wọn sin ni ṣekere wọn mu ọna Igboro pon wọn beresi kọrin kiri. Bayi ni wọn nkọrin ti wọn ngbokiti pelu ijo alarabara fun odun meji ki wọn to kan ilu ti Abaja fi ara pamọ si. Bi nwọn ti de ilu yi wọn bere ijo wọn lati ọja. Okiki ijo wọn kan lọ ba Abaja nile nibiti o gbe gunrun sara tim-tim ti o si nje onje alegbadun lọwọ

Ni ikehin wọn kan Stese-lese Abaja eniti ara nfu pupo lati jade si awọn akorin aleje yi ṣugbọn awon omo ati iyawo re gbaaiyanju lati ta awọn akorin lọrẹ.

(koiti pari)

## Azikiwe D'omo Orukan



Eniti a nwo ninu aworan inu iwe wa yi ni Dokita Nnamdi Azikiwe ti ise Alakoso Ijoba Ila-Orun (Prime Minister Eastern Region) On ni Iya re jalaisi ninu osu January, odun yi.

Lehin tun kan wa ni ojo Alaruba (Wed.) ojo kerin osu yi wipe baba Dokita Azikiwe tun file bora bi aso, nigbati o di eni odun mejidinlogorin, lehin osu meji pere ti iyawo re fi ile aiye sile.

ENI OMO SIN LOBIMO

Ni ede ti awa Yoruba nje Dokita Azikiwe ṣe ori rere lati ri ẹhin awon ota re mejeji; ki Oluwa fi wọn si afefe rere.

A ki Dokita Azikiwe ati awon ẹbi rẹ ku aechinde ẹhin awon oku na n dara o.

Let's have MUSIC! HEAR THE LATEST HIT NUMBERS



Read this list of popular titles

HMV YELLOW & RED DOG
J2 6098-Kelegbe Megbe/Odun Titun
Owo Titun
" 6099-Agba Olorin/Busura Baba Osu
" 6100-Yawa Yesu/Omolere Aiye
Jimo Ojindo
&
his (Sakara) Band

OBTAINABLE FROM:-
1. Y.A. Bilesanmi -87, Victoria St. Lagos
2. Animawun Stores-24 " " "
3. Salawu Aremu -73 " " "

HMV BLUE DOG
J2A 100-Shogbolo/Oluwa Gbawa Lowo Iku Ojiji
" 101-Bakare Alake/Ejire Baba Taju
" 102-Raimi Oga Ota/Wahabi Baba Fasila
S. Aka & his (Sakara) Band

OBTAINABLE FROM:-
Omobori-Owo Stores
Lagos/Abeokuta.

Sold by all the best stores

"HIS MASTER'S VOICE" Yellow label RECORDS

Distributed by THE UNITED AFRICA COMPANY OF NIGERIA LIMITED

# Awo Rekodu Decca

(Titun Ti o Sese de)

WA 1985 Bisi Dan Seria
" 1984 Alfa Saka
" 1989 Salawa Aiyepe
" 1991 Atunbo Tan Aiye
1888 Olowu Birin
" 1995 Lukuluku (Apala)
" 1992 Abowonle (Apala)
" 1993 Orin Alabada (Apala)
" 1994 Orin Oyinbo (Apala)
" 3011 Janba Railway (Agidigbo)
" 3012 Oro Isiti
" 3013 Alhaji Tafawawa Balewa
" 3014 Ore Sododo
" 3015 Nifaji Kalelo
" 1976 Oro EKo

WA ra won ni Sopu wa.

**Egba Trading Aradan Stores**
18, Denton Bridge Street, P. O. Box 2
Ebute Metta & Branches

# Oloye Akintola Fi Ero Isoro Titun Ba Sardauna Soro

(O bere loju ewe kini)

Mo mbe nihin Kilo fe?

SLA - Mo fe ba Sardauna Sokoto soro.

Olotu - Kaduna Kaduna Eko fe ba Sardauna soro

Sardauna - Emi Sardauna Sokoto mbe nihin

Olotu Eko, ma soro nigo.

SLA - Emi Akintola Minister oro Isoro ni Eko lo nsoro.

Sardauna - Ha! O se pupo Se ko si nkan?

SLA - E ku ise o awon ara Eko ni ki nki o, se alafia lo wa?

Sardauna - Ha! o se pupo bakanna ni ni awon Hausa ki nyin a si ni ireti pe alafia ni e wa.

SLA - Iwo ni mo ko ko fe ba soro loni nitori ki e le je pe ire ni eni akoko ti yio soro sinu ero n a lati Oke-Oya wa.

Sardauna - Inu mi dun lati gbo be sugbon anfani wo ni a le ri nibe?

SLA - Eyi yio fun wa ni anfani lati le ba ara eni soro kia-kia, ati lati tete ma ri wa yagba.

Sardauna - Inu mi dun jojo lati gbo be nitoripe eyi yio je ilosiwaju ni Ila Orun Iwo Orun ati nile Hausa pelu.

SLA Boti ri gan na ll o wi yen nitori ibi ti mo ti duro si ti mo gba osoro yi si odo re je edegbaa ibuso ero isoro titun yi lo si tobi julo nigbogbo aiye.

Sardauna Ise nla ribi-ribi ni eyiti o se yi bakanna lo si ye ki a yin awon ti o se ise na. Mo ki o gidigidi ati awon osise re ti e fi se ise n a yeri. Ilosiwaju ni eyi yio je nile Hausa ati nigbogbo ile Nigeria.

SLA Gegebi iwo papaa yio ti ri ninu iwe ti ao se jade ona wa si jin ti a nlo gbogbo ogbon ori wa ni a ti lo si idi ero isoro na tan Mo dupe lowo re o digba o se

Sardauna O digbose o.

**ORIN BABALAWO**

S'otito S'ododo eni Sotito ni Mole yio gbe o.

# Education

Before the universal primary education scheme came into operation in the Western Region, the number of children attending primary schools was 456,000.

With the introduction of the scheme in January 1955, 391,895 children were admitted to Primary Class One alone.

A total sum of over £4 million has been spent on primary school buildings. An additional expenditure of over £3 million on primary school expansion has been approved.

Government has given over £½ million as building grants to Teacher Training Colleges, and over £1 million as grants for Training Teachers.

A total of £274,809 has been paid in grants to Secondary Grammar Schools in the Region during the past four years.

More Secondary Modern Schools and Trade Centres are being established to ensure that practical as well as academic education is encouraged.



*Issued by the Western Nigeria Information Services*

Printed & Published by The Union Printing and Publishing Company 28, Kosoko Street P.O. Box647 Lagos Phone 23370